# Irin ajo Juli ati Ola lo si inu ile nibi ti omi ti nsun.




Itan lati owo Leanne Appleby ati Peter Russell
Fortunato Restagno lo ya awon aworan inu iwe yi
Yoruba translation by Oluwole Ayinde Oyedeji Ph.D

Odun 1993 Agbara atunte oro kiko wa lowo Leanne Appleby ati Peter Russell
Odun 1993 Agbara atunte aworan inu iwe yi wa lowo Fortunato Restagno
Atunte alakoko ni a se ni osu kokanla odun 1993(ede Geesi)
Atunte eleekeji ni a se ni osu keta,  odun 2017(ede Geesi)
Gbigbe iwe yi  sori ero aiye lu jara eleeketa ni a se ni osu keje odun 2020 (ede Geesi)
Gbigbe iwe yi  sori ero aiye lu jara eleekerin ni a se ni osu kewa odun 2020 (ede Spanish)
Gbigbe iwe yi  sori ero aiye lu jara eleekarun ni a se ni osu kejila odun 2020 (ede Giriki)
Gbigbe iwe yi  sori ero aiye lu jara eleekefa ni a se ni osu keji odun 2021 (ede China)
Gbigbe iwe yi  sori ero aiye lu jara eleekeje ni a se ni osu kesan odun 2021 (Faranse)
Gbigbe iwe yi  sori ero aiye lu jara eleekejo ni a se ni osu kesan odun 2021 (ede Indonesia)
Gbigbe iwe yi  sori ero aiye lu jara eleekesan ni a se ni osu kesan odun 2021 (ede Hausa)
Gbigbe iwe yi  sori ero aiye lu jara eleekewa ni a se ni osu kewa odun 2021 (ede Hungary)
Gbigbe iwe yi  sori ero aiye lu jara eleekokanla  ni a se ni osu kewa odun 2021 ede Afrikaans)
Gbigbe iwe yi  sori ero aiye lu jara eleekejila ni a se ni osu kejila odun 2021 (ede Urdu)

Gbogbo ase wa lowo
Ile iko nkan to o je mo imo ijinle nipa aiye.

ISBN 978-1-7778409-8-3

Ile iko nkan to o je mo imo ijinle nipa aiye ti o wa ni Ile eko giga ti Waterloo, ni Ontario, Canada N2L 3G1 lo nse agbateru bi a se npin iwe yi

Oluwole Oyedeji lo se titumo iwe yi si ede Yoruba

# Irin ajo Juli ati Ola lo si inu ile nibi ti omi ti nsun.

Itan lati owo Leanne Appleby ati Peter Russell
Fortunato Restagno lo ya awon aworan inu iwe yi
Dokita Oluwole Ayinde Oyedeji lo se titumo iwe yi si ede Yoruba

A dupe lowo
Deanna Armstrong
Ti o ngbe ni Youngstown, Alberta
Eni ti o ko iriri ekolo kan nipa
omi ti o wa ninu ile



Juli, ekolo ti o ngbe ninu ile fo jade pelu apo agbeko ehin re. O soro soke “ ah, ojo titun ojo ti o dara lati ni iriri titun re e,”. Kurukuru nkora jo loju orun. “Hum, O dabi eni pe ojo fe ro.” Eyi ni ero Juli bi o se nwo lo lori ile.



Ni awosanma nigba ti Juli boju wo oke , Ola ati awon ore re ti won je ojo ti o fe ro na korajo fun iriri titun.



Juli gbe oju re soke bi o se ku die ki Ola bale sori ile. Juli gbe owo re soke lati mu Ola. Awon isan omi yoku ti won nba Ola bo na bale. Awon kan nsan lori ile nigbati awon kan wa ona lati wo inu ile lo.



E jeki a fi oju inu wo ero ti o nlo ni okan Ola nigbati o ri wipe oun nikan lo ku ti ko wo inu ile lo.



“ Ola wa ke ni ohun rara pe, ‘Emi ni Ola isan omi, emi na fe wo inu ile gegebi awon isan omi yoku ti o je ore mi!” “O fe wonu ile ke?” Juli bere lowo Ola. Juli fo kuro lowo Ola, o wa se alaaye fun pe “Nigbati ojo ba ro, omi ti o ba bale sori ile, die yio san, sugbon awon kan yio wo inu ile lo.! Nje o fe ba mi rin irin ajo lo sinu ile bi?”



“Duro de mi Ola” Juli fa oko re jade lati apo agbeko ehin re, o si gbe iho lo sinu ile. Ni ibere, o rorun fun lati gbe ibi ti o je yanrin. Bi o se ngbe lo si isale, iyepe yi bere si wuwo, o si le lati gbe. “Ise yi le die o!” Juli pariwo.



Iho yi ma ti bere si kun fun omi, o ya Juli lenu ‟. Kia lo mu nkan idabo imu re ki o le le Ola ba.



“Eleyi rorun lati gbe ni Juli nso ,” bi o se nti awon okuta wewe seg-
be..



“Mo ki o ku abo si ibi ti omi ti nsun, Arakunrin ekolo,” beni Ola wi fun Juli. “Rara, o, Juli loruko mi.” “Ola ni ohun ti gbo, sugbon iwo Juli, wo ayika re.”. A ti wo inu ibi ti iyepe ati okuta wewe ti wa po, ibi ti omi ti nsun.”



Awon ore Ola koja ninu okuta wewe ati yanrin. Won nwa ona bi won se ngba inu ile yi koja nibi ti omi ti nsun.



Juli tera mo ile ti o ngbe yi ninu yanrin, o nsa ipa re lati le Ola ba.



Juli ati Ola wa de ibi kan ti o dabi eni pe omi ti wa nibe tipe. Juli bi Ola pe ‘Kini itumo nkan ti mo nri yi?” Ola wa so fun pe iru isun omi miran ni. Ola se alaaye fun Juli pe nigbati yanrin yi ba kere si, ti won ti fe di amo, awon alafo ti o wa laarin won a ti kere si, ti omi o ni ri aaye lati koja. Bi o tile je pe awon kan a ri aaye koja, opolo-po ni o ni ri ibi koja, a gba won ni asiko die ki won to le koja’’.



Bi won se nlo ninu irin ajo won, won se akiyesi pe ona nla fun won bi won se nsunmo opa agbomi ti a ti ri bo ile ninu yanrin. '' E gba wa o '' ni igbe ti Ola ke, a ti nfa wa lo sinu kanga." ''Kanga ke", Juli beere lowo Ola.



‘’ Ola so fun Juli pe Awon eranko kan ti won ngbe ori ile ti ri opa agbomi onirin sinu ile lati fa omi jade “Okan lara awon eranko yi ni oruko re nje Arakunrin Martin ti o nfa omi jade lati fun awon elede re. Die lara omi ti o nfa lo nda sile ti o tun nwo inu ile pada.



Won koja legbe kanga yi. Ola sakiyesi pe awon ore re ti wa nmookun ninu isun omi. O wa bere lowo Juli pe " Nje iwo na le mookun bi?'. ''Rara'', ni idahun Juli. Bi o se wu ko ri, je ka pada soke nibi ti ko si isun omi nibiti awon ore re wa, Ola so fun Juli.



“Ah,ategun alaafia wa nibi! Ah, Juli so fun Ola pe, Ojo ti da, ni o ba yo ibomu re kuro.



Won ba joko si ori apata kan to loworo. Ola wa bi Juli lere pe bawo ti e ni irin ajo wa yi se gun to?. Juli da lohun pe ‘O ya wa ni isin yi. Ola wa se alaaye pe ti a ba sare bi awon ore wa ni, o le gba wa ni asiko die, bi ose die tabi odun die lati de ibi ti a wa yi.



Ola wa ri wipe oru ti nmu ohun, ohun ti e nlaagun. Ola wa so fun pe ki o ma se beru, ara irin ajo won na a ni. Inu ohun yio dun lati ri laipe ojo.



Oogun ti Ola nla wa ngoke re oju orun . ‘Mo dupe gidigidi lowo re’’ ni Juli nso. ‘’O se e fun irina ajo nla ti o mu mi lo. Inu mi yio dun lati ri o laipe.



Nigbati gbogbo oogun Ola ti goke lo tan, Juli bere si ma ronu si iriri ti o ri ninu irin ajo won yi. O sese wa ye mi yekeyeke bi omi se nrin lati oju orun wa si ori ile, lo si inu ile ati ipada soke re. O wa mo pe, oun yo tun ri Ola leekan si.

# Itumo awon oro ti a lo ninu iwe yi

## Isun omi ninu ile

Ibi yi ni o le je okuta tabi iyepe ti o wa labe ile ti a le ri omi nigbati a bag be kanga . omi ti a ba ri yi yio wulo yio si to fun ilo wa ninu ile, oko, ni aba, tabi ilu. Omi ma nri aaye lati rin ninu ibi yi.

## Amo tabi okuta ti o le

Eleyi le je okuta , tabi amo ti ko ni gba omi laaye lati koja, ko ni le fun wa ni omi ti yio to fun ilo ile tabi ise miran.

## Ooru ti o njade ni inu omi ti o ba gbona

Ti a ba gbe omi kana to o ba ho, ooru ti o ma njade nibe ma ngoke lo si oju orun. Eleyi ni iyipada omi si ooru. Orun naa ma nse eleyi nigbati o ba sise lori omi ti o wa lori ile. Ohun ni o ma nje ki omi ti o ba wa lori ile ki o gbe lehin ti ojo ba ti ro.

## Bi omi se now inu ile

Nigbati ojo ba ro, eleyi ni bi omi se nwo nnu ile lo. Omi yio gba inu okuta ati iyepe koja.

## Bi awon eweko se nda omi pada sinu afefe

Awon eweko na ma ngbe omi sori ewe won lowuro kutukutu. A le ri akawe eleyi ti eniyan ba mi si ara iwe tabi diigi papapa nigba ti otutu ba mu.

## Ibi ti omi o ti wa ninu gbogbo alafo ti o wa laarin iyepe ati okuta

Ibi yi ni ibi ti o je wipe ki i ise gbogbo alafo ti o wa laarin awon okuta wewe tabi yanrin ni omi wa. Ohun lo wa loke ibi isun omi. Ni asiko ojo, apa kan nibi yi ma kun fun omi eleyi ti o je ki ibi isun omi wa soke. Ni asiko erun, ibi isu omi a lo si isale si.

## Irin ajo omi ti ko nipekun

Omi nrin ni ipa ona ti ko lopin. Nigbati ojo ba ro, die, a wo inu ile lo, die, a san lori ile, won a wo lo sinu odo ati okun. Nigbati oorun ba pa awon ti o wo inu odo ati okun, won a goke lo si orun gegebi ooru. Li oju orun awon eleyi a tun di kurukuru ti won a tun ro bi ojo , ti won a tun pada sile.

## Ibi ti o kun fun omi ninu ile

Ibi yi ni ibi ti o je wipe omi ti nsun ninu ile, ti omi ti wa ninu gbogbo alafo ti o wa laarin yanrin ati iyepe

## Ibi ti omi nde ninu kanga

Nigbati a ba gbe kanga, ibi yi ni omi yio duro si ninu kanga to o nfi han wa ibi ti omi po si ninu kanga. Ni abe ibi yi, gbogbo alafo ti o wa laarin okuta ati iyepe ni omi kun.

**Ooru omi**
Oooru ti o njade nigbati oorun ba la omi to wa lori ile yio goke re oju orun. Nigba ti won ba su po daradara, won a wa o bi ojo

**Kanga**
Iho ti a gbe tabi kanga ti a gbe lo sinu ile lati fa omi jade. A o ri opa igbomi ti a ri bole wo inu isun omi yi ni ori ile.

Ile bi ti a nko nkan nipa imo aiye ati awon alumoni re ti o wa ni Ile-eko giga ti Waterloolo lo gbe iwe yi jade, labe akoso ti ibi ti won ti nse iwari imo ijinle ti Omi ti o wa ninu ile pelu ifowosowopo ile ise ti Edviro eyi ti o wa ni Waterloo ni Ontario, ni orile ede Canada ni odun 1993.
Leanne Appleby ati Peter Russell lo ko Itan yi, Fortunato Restagno lo ya awon aworan.


FORTUNATO RESTAGNO © Oct. 1992

EARTH SCIENCES
museum
UNIVERSITY OF WATERLOO

https://uwaterloo.ca/earth-sciences-museum/

A te iwe yi  ni orile ede Canada

Ni orile ede Canada ni a ti te iwe yi